# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV No 536 LAGOS SATURDAY SEPTEMBER 8, — SEPTEMBER 14 1962.


OKU RA POSI:

## Koniyekan Olowo San Owo Isinku Ara Re

CROMER (England) — Nwọn ni oku ki ra posi ni a ti ngbọ ni aiye atijọ, sugbọn Ọgbẹni olowo ara ilu Oyinbo kan ti orukọ rẹ njẹ Robert William Clarke ti o ngbe adugbo kan ti nwọn npe ni Guys Cliff ni ilu Cromer ni ọtọ ni ti on, on nilati ra posi ati asọ ti nwọn yio fi sin on silẹ nitoripe on ko lara, on ko si ni iyekan ti nwọn yio sẹhin de on bi on ba ku.

Irohin ti onirohin wa fi ranṣẹ si wa nipa Ọgbẹni ologbe na ni wipe ọmọ ọdun kandinladọrun (89) ni ki o to ku, ko si fi igba kan lobinrin nile ni gbogbo ọjọ aiye rẹ.

Nigbati o ku ẹgbaa mọkandinlogoji o le oko dinlẹgbẹta (£78,580) ni owo ti nwọn ba lọwọ rẹ, ti ko fara gun gbese kan rara. Kosi nkankan ti awọn ara adugbo ọkunrin na ṣe akiyesi pe o yatọ si ti ara yoku ninu ilosi Ọgbẹni na nigbati o wa

(Wo yoku loju ewe kejọ)


### NIGERIAN PORTS AUTHORITY

INVITATION TO TENDER

CONTRACT FOR SUPPLY OF LABOUR FOR

(a) "C" WAREHOUSE, APAPA QUAY

(b) "D" WAREHOUSE, APAPA QUAY

The Nigerian Ports Authority invite tenders from Contractors to supply experienced labour with adequate supervision for the handling of cargo at "C" and "D" Warehouses, Apapa Quay.

2. Tenders which must be submitted on forms provided by the Authority for each warehouse separately and returned in sealed envelopes maked "CONFIDENTIAL—TENDER FOR LABOUR "C" (or "D" as the case may be) WAREHOUSE" should be addressed to the Secretary to the Authority, Nigerian Ports Authority 216, Broad Street, Lagos, so as to reach him not later than 4 o'clock in the afternoon of Monday, 17th September, 1962.

3. Tenderers may tender for either one or both of the two warehouses.

4. Persons tendering for "C" Warehouse must use the Form of Tender bearing "C" Warehouse and persons tendering for "D" Werahouse must use the Form of Tender bearing "D" Warehouse.

5. The issue of an official form of tender will be subject to a deposit of £10 for each werehouse, payable to the Authority's Cashier Accounts Department, Apapa Quay. The deposit will be returned on receipt of a bona fide tender.

6. Only applications from labour contractors who have had experience in similar work will be considered, and the Authority do not bind themselves to accept the lowest or any tender.

7. Applicains wishing to view either "C" or "D" Warehouse or both before submitting tenders should apply in person to Chief Traffic and Commercial Manager, Apapa Quay.

BAYO KEHINDE

Secretary to the Authority.

N. P. A. Notice No. 761

30th August, 1962.



### THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1933

Paid up Capital £3,181,000

HEAD OFFICE

82/86, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA.

Bankers to the Western Region Government of Nigeria

DIRECTORS:

SAMUEL LAYIWOLA DUROSARO-Chairman Managing Director ABDUL AZEEZ OLAYIDE DUROSHOLA-General Manager AYOTUNDE OLATUNDE OSHINIBI

LONDON OFFICE

15, THROGMORTON AVENUE, E. C. 2.

Manager J. F. Burton.

Telephone London Wall 4303 — Cable & Telegrams Natbaniger; London

Head Office Representative in London.

E. Akinwumi Doherty,

CORRESPONDENTS

NEW YORK PARIS HAMBURG

30 Branches Throughout Nigeria Including

IBADAN. BENIN-CITY. SAPELE. ABA. KANO. ZARIA. JOS.

# Awo Irawo

## E yi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbo.

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20)
Wa ri imọran daradara kan nipa Igbesi aiye rẹ lọsẹ yi, ki o si gba imọran ti ẹbi rẹ kan yio fun ọ.

PISCES (Feb 21-Mar 20)
Bi iwọ ti o nka eyi ba jẹ ọkunrin ki o dira rẹ mu dada nitoripe ọrọ obinrin yio ko jinni-jinni ba ọ; bi o ba si jẹ obinrin yio mu ọ lọtutu.

ARIES (Mar 21-April 20)
Ọrọ ifẹ tebi nipa ọrọ abẹ ọdẹdẹ a jẹ ki o pe ọsẹ yi ni pataki

TAURUS (April 21-May 20)
Ọsẹ idẹra leyi fun ọ; iwa tuntun, enia tuntun, gbogbo nkan lọtun lọtun ni fun ọ.

GEMINI (May 21-June 21)
Bi o ba lọ soja lọ ra nkan wa ri apa enia ba naja.

CANCER (Jun 22-July 23)
O nro ero kan lọkan nigbagbogbo, ero yi a si yọri si rere fun ọ lẹhin ọjọ ọla.

LEO (July 24-Aug 22)
Ọsẹ yi fọ rere fun irin ajo ti ko jinna pupọ ti o ko ba ti jẹ ki nkan ti o wa lọna jinjin gba ẹ lọkan.

VIRGO (Aug 23-Sept 23)
Irawọ rẹ ni wa ri awọn ọmọde ba ṣere lọsẹ yi.

LIBRA (Sep 24-Oct 23)
Nipa aisan wẹrẹwẹrẹ ti o nṣe ọ, ẹnikan yio ba ẹ da imọran, ki o gba a.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22)
Wa ṣe alabapade iṣegun ti o ko nireti kan, lẹhinna ọrọ ẹ jẹ mọ a nlọ sode.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22)
Wa ba awọn kan ṣe ariyanjiyan ṣugbọn ọrọ tirẹ ni a mu ogbọn dani.

CAPRISCORN (Dec 23- [illegible]n 21)
Nkan awọ elewuro, namba 12 ati orukọ ti L ba bẹrẹ rẹ dara fun ọ.

---

IBOSI OLE TI

# O Gbe Owo Ogun Oju Lo

SAPẸLẸ—Ibanujẹ pẹlu ayọ dapọ mọra wọn ninu ile Ọgbẹni kan ti orukọ rẹ njẹ A. J. Achomaru ẹniti o ṣe iṣẹ ọdun mẹrindilogun lọdọ awọn Oyinbo onipako, African Timber & Plywood Company, ki nwọn to da a duro lẹnu iṣẹ pẹlu ọgọjọ oṣiṣẹ miran; nitoripe ole gbe ẹdẹ-gbẹjọ pọnun (£1,500) ti awọn Oyinbo ibi iṣẹ rẹ fi rẹ ẹ lẹkun lọ.

Onirohin wa sọ fun wa wipe gbara ti nwọn ti da ọgbẹni yi duro lẹnu iṣẹ ni nwọn si ti san owo na fun un, ti on na si gbe lọ pamọ sinu iyara rẹ. Ni ijẹrin ni awọn ti nwọn jọ nṣe iṣẹ pọ sọ wipe o yẹ ki awọn ṣe aṣeyẹ fun ọgbẹni na nitori iwa rẹ dara pupọ.

Ibi aṣeyẹ ni o lọ, on ati awọn ara ile rẹ ti nwọn si ngbadun pẹlu awọn ti nwọn nṣe aṣeye na fun un lọwọ ki irohin [illegible] to kan an pe awọn ọlọṣa ti fọ ile rẹ, nwọn si ti gbe owo ogun-oju rẹ lọ tefe-tefe.

Awọn ọlọpa'nu si ti fi ẹsẹ bọ sokoto lati ma se iwadi awọn ti o ṣe iṣẹ buruku yi.

---



# Alufa — A g b a Kan Gb'oye

LOND N — Dokita Michael Ramsey (ti o wa ni apa osi ninu aworan yi) ni Bisọbu agba Ijọ Ṣọṣi C.M.S. gbogbo agbaiye ti o fun Alufa Leonard J. Beecher ti Ijọ C. M. S. ni East Africa ni oye gigi-kan nipa ọna ẹsin ti Ọlọrun laipẹ yi ninu agbala Bisọbu ti nwọn npe ni Lambeth London.

Ni ilu London ni nwọn ti bi Alufa Beecher ti nwọn ṣẹṣẹ fun ni oye nla yi, sugbọn o ti se ọdun mẹrundinlogoji [illegible] enia dudu ilẹ orun Afrika ni Kenya, on ti o si ṣe iwe-gbedegbẹyọ (Kikuyu Dictionary) fun wọn ni [illegible] na.

OMO ONikoyi Ni:-

# Awa Omo Eko Kise Odale

OLOTU, inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi laye ninu iwe yin gẹgebi ẹ ti gba awọn ara yoku laye, awọn bi Ijẹbu ti o pe ara rẹ ni ỌMỌ ỌBANTA, Ẹgba ti o pe tirẹ ni ỌMỌ Lisabi ati ọmọ Hausa ti o ni on ALHERI, lati sọrọ diẹ sinu Eleti-Ọfẹ. Ọwọ yin yio mọ roke, iwaju ni ẹo ma lọ.

Awọn agbalagba ni nwọn pa owe wipe "bi iya nla (iya-jijẹ) ba gbeni sanlẹ, awọn kekere iya a ma gun ori ẹni" ni ti ọrọ rukerudo ti o ti bẹ silẹ, ti ẹniti o tọ si nsọ tirẹ, ẹniti ko tun tọ si na tun sọ tirẹ.

Nwọn onigba ni pe igba rẹ ni aakara ti a fi ba a kolẹ. Ẹẹkẹ ebu kọ ni mo fẹ ṣe sugbọn mo fẹ ki gbogbo ọmọ Karọ-jire mọ nkankan daju; nkan na ni pe awa ọmọ Eko kiṣe ỌDALẸ. Awa ki fẹ balẹjẹ. Loju ọpọlọpọ awọn ẹlomiran, emugọ ni a jẹ, bẹ nwọn ni "laala ti o roke ilẹ ni o mbọ pada wa."

Ki a ti ibi ọrọ iṣana kiyesi ẹtu, lati ọjọ gbogbo ti awọn ti nwọn f'oju omugọ wo wa yi ti nda gbogbo nkan ti nwọn yio da nigba ati eyiti nwọn yio da l'awo, ti nwọn ba firu fọnna lọdọ wọn tan, ilu Eko yi na ni nwọn ngbe bọ.

### Eko Ile

Ki a wa sọrọ ọmọlẹbi, ọpọlọpọ awa ọmọ Eko (nko sọ ti ara Eko o, nitoripe awọn yẹn wa lapa kan) ni yiya ti nwọn yawa kuro lọdọ awọn ọmọ iya wa dun wa pupọ. Mo niran pe Gomina-agba kan ti o ti ṣe iṣẹ ni ilẹ yi ri sọrọ ni ilu Oyinbo lori yiya na (seperation of Lagos), o ni "a nrẹ awọn arabi yi jẹ ni o, Yoruba ni o ni Eko."

Ẹ ba gbe olu-ilu (Capital of Nigeria) lọ si Kanọ tabi Kaduna, Port-Harcourt tabi Nsukka, ọla ti Ọlọrun fi fun ilu Eko ko ni kuro nibẹ. Kinni a tilẹ ṣe ti ẹ fi nko iyan wa kere?

Awọn ọmọ akọrin ti ro ọrọ na ki awọn to fii kọrin bayi.

Eko ile, Eko gb'ole o gb'ọlẹ,
Yeyeye, Eko gb'ole o gb'ọlẹ.

Awa ọmọ Eko ko ni ọrọ pataki ti a fẹ sọ si ọrọ rukerudo ti o de ba gbogbo Nigeria (kiṣe Ipinlẹ Iwọ Orun nikan) ju pe ki a mọ woran lọ, ki mọ wo ibiti yio jasi, ki a si ma gba adura wipe ki gbogbo rẹ yọri si rere.

Ṣugbọn nkankan ni mo fẹ tẹ mọ gbogbo ẹnyin ọkawe Eleti-Ọfẹ leti, awa ọmọ Eko kiṣe ỌDALẸ nitoripe ẹnikẹni ti o ba DALẸ, A BA ILẸ LỌ.

Abọ ọrọ ni a nsọ fun ọmọluwabi bi o ba si de inu rẹ a di odidi. Ọmọ Onikoyi ti sọ tirẹ, O digba!

## Taylor Baba Ile Owo Gba Isinmi

EKO—Ọgbẹni W. Taylor ẹniti o ṣe iṣẹ fun ọdun mẹtadinlogoji (37) ni Banki ile ifowo pamọ kan ti nwọn npe ni Bank of West Africa (BBWA ri) laini abawọn lara ni a gbọ wipe o gba isinmi lati fi iṣẹ silẹ ni ipari oṣu ti o kọja yi.

Ni ọjọ Aiku (Sunday) ijeje ni Ọgbẹni Taylor pẹlu awọn ọmọlẹbi ati ọrẹ rẹ lọ si Ṣọsi Ijọ C.M.S. ni Broadfruit lati lọ ṣe isin idupẹ wipe on gbe iṣẹ na dori. Alufa Ọrẹdugba ni o ṣe isin-idupẹ na fun wọn.

Lẹhin isin yi gbogbo awọn enia ba Ọgbẹni Taylor lọ si inu ile ti o ngbe ni 15, Akinwumi Street, Yaba nibiti o gbe ti fi nkan jijẹ ati nkan mimu tẹ gbogbo wọn lọrun.

Ọgbẹni Taylor jẹ ọkan ninu awọn ọmọ baba oninure Ologbe Adejọ Taylor ni Agọ Ọba ni Abẹokuta, iṣẹ ti o nṣe ni ile ifowo pamọ si na si ti gbe kakiri gbogbo ilẹ Nigeria.

Awa Eleti-Ọfẹ ki nyin, alagba, ẹ o lo isinmi na pẹ o.

# Eka

**Irohin Ayiluka**

**Loju Ewe Karun**

# Awon Ara Idita Fi Okuta Ipile Mosalasi Won Lele

EKO-Ni owurọ ọjọ Aiku (Sunday) ti o koja yi ni awọn ara Idita ni Olowogbowo fi okuta-ipile Mọsalasi tuntun ti nwọn ṣẹṣẹ nkọ lelẹ loju gbogbo ogunlọgọ awọn enia lọkunrin ati lobinrin ti nwọn pejọ ṣiba ṣiba sibẹ. Ki akoko ti nwọn fi sinu iwe ti nwọn fi pe nwọn to to ni awọn enia ti rọ kunle.

Awọn ti nwọn yan ni alaga aṣeyẹ ọjọ na ni Ọgbẹni Yẹkini Ajadi Adelagun (ẹniti gbogbo enia mọ adape orukọ rẹ ni Faramọbi) ati Ọlọla S. L. Edu, Kọmiṣọna alamojuto eto ilera fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun; Ọlọla Edu ko le wa si ibi aṣeyẹ ọjọ na ṣugbọn o ni ki Alhaji M. A. Tijani ṣe aṣoju fun on. Alhaji Tijani na ni o si ṣe gbogbo nkan ti ko ba se nibẹ lọjọ na.

Gbara ti gbogbo ẹsẹ awọn enia ti pe si bẹ tan ni Lemọmu Yisa Onigbanjo ba fi adura ṣi aṣeyẹ ọjọ na. Akọwe awọn igbimọ ti o nṣe eto kikọ Mọsalasi na, Ọgbẹni L. Ọmọtẹṣọ Saaka ni o kọ sọrọ, ti o darukọ alaga ati awọn isọngbe rẹ si eti gbọ gbogbo awọn enia; lẹhin eyi ni alaga paapa Ọgbẹni Adelagun (Faramọbi) wa tẹnu bọ ọrọ nipa bi awọn agbalagba Idita ti ma nṣe si awọn nigbati on ati awọn ẹlẹgbẹ on wa lọmọde. O ni inu on si dun gidigidi si pipe ti nwọn pe on, ti nwọn si gbe on ga lati ṣe alaga ọjọ na.

Siwaju eyi, Ọgbẹni Saaka, akọwe, ti sọ itan bi awọn agbalagba Idita ni aiye tiṣe ran Ologbe Daddy Karimu Thompson lọ si ọdọ Oloye Onitọlo pe ki o ba awọn tọrọ ilẹ ti awọn kọ Mọsalasi na si. Eleyi si ni ẹkẹta ti nwọn tun un kọ; ni akọkọ, igi-ọpa ni nwọn fi kọọ, ikeji amọ, ki o to wa kan eyiti nwọn nkọ lọwọ yi.

(Wo iyoku loju ewe kẹfa)

Advt. No. 151

**Se o ti lo paro owo atijo owo re**

SI OWO TUNTUN ti ilẹ Nigeria ? O le parọ OWO PEPA kọrẹnsi L'ỌFẸ TITI DI IPARI OṢU SEPTEMBER Ti a wa ninu rẹ yi.

**Ti owo sile ati awon isongbe re di ipari osu**

DECEMBER.

# ELẸTI-OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI OFẸ," LAGOS
P. O. Box 468 Phone 23370.

VOL XIV. No. 836. SATURDAY SEPT. 8, - SEPT. 14, 1962


# OWO TUNTUN

NWỌN ni bi a ba nsọkun a mọ nriran, nitorina o yẹ ki a ran ẹnyin ọkawe wa lọmọde lagba leti nipa ikilọ pataki kan ti awọn olotu Ijọba Apapọse ti tun gbe jade nipa owo atijọ ti a ti nlo ti nwọn sọ wipe awọn fẹ ko kuro nilu.

O to oṣu mẹrin nisisiyi ti awọn olotu Ijọba na ti nsọ fun wa wipe ki a tete ko awọn owo na lọ si ile ifowo pamọ (Bank) ki a lọ parọ wọn lọfẹ, sugbọn a gbọ wipe awọn miran ko tilẹ bikita lati se bẹ nwọn ti nna awọn owo na lọwọ lọwọ nisisiyi. Awawi ti awọn miran nsọ ni wipe awọn ko le ti tori owo ti ko to nkan lọ to si Banki, ki awọn ma fi akoko s'ofo.

Awa Eleti-Ọfẹ mu eyi wa ni imọran pe, ẹnyin ti e ba wa ni ileto kan, ki ẹ so'wo pọ, ki ẹ ko gbogbo owo atijọ nyin fun ẹnikan ki o wa si Banki arin ilu, ki o wa ba nyin ṣe iparọ rẹ. Agbojọ ki gba ọjọ kan ti.

Ẹ tete lọ parọ owo atijọ ọwọ yin si tuntun nitori lẹhin oṣu yi ẹo ma san owo lori rẹ fun awọn ti o ba ba nyin parọ wọn.

# Eko Akoju Ba Won Lori Je

AWỌN Yoruba ni ede-ọrọ ko-ba-ikun-gbe kan ti nwọn ma nlo ti nwọn ba ṣe akiyesi wipe ẹnikan nfẹ gun igi koja ewe, nwọn a ni "Falana gbọ tire, Yara ẹni ni a gbọ," iyẹn ni imọran ti ao ba awọn ọmọ ileve kan ti a gbọ wipe kaka ki nwọn tẹju mọ iwe ti nwọn ran wọn lọ kọ ni ilu iwe-giga, ọrọ awọn oṣelu ni nwọn fẹ ma yọju si.

Nitotọ aiye ti di ajye ominira, nkan ti o wu ajukuluku ni o le fi ara rẹ ṣe ni ode ti isinsinyi, sugbọn bi ti ki a ka ẹsẹ mejeje soke ki a ma fi ori rin kọ.

Awa oniwe Eleti-Ọfẹ ko wipe ko nse ẹtọ ẹnyin ọmọlewe yi lati ba wọn dasi ọrọ oṣelu, sugbọn a ri wipe a ba oju mu, a si rọ nyin lọrun pẹsẹpẹsẹ bi e ba le mu suru di igbati ẹ ba kọ ẹkọ yin ni kikun tan, ti ẹ le fi ẹsẹ bọ sokoto lati ba wọn ṣelu.

Nwọn ni ko si igba ti a da aṣọ ti a ko ni ri ile fi wọ.

Ẹ ṣe ọrọ na ni Falana gbọ ti ara rẹ, ti ara ẹni 'aa gbọ.

# Iwe Si Iotu

# Omo Lisabi E Gbere !

OLOTU,

Mo gbadun ọrọ ti ọkan ninu awọn ọkawe yin ti o pe orukọ ara rẹ ni Ọmọ Lisabi kọ lapẹ yi. O ni awa Ẹgba korira ọtẹ pupọ nitoripe nṣe ni ọtẹ ntẹ enia. Ododo ni ọrọ na.

Ọrọ ọmọ Lisabi yi jẹ ki nniran igbati ilu Ẹgba toro ti a roju ti a si raye ki o to di ọdun 1914 ki awọn kan to ko ọtẹ bọ awọn oṣelu Ẹgba igbana.

Awọn kan rojọ ọtẹ mọ Ọba Alake ti o wa lori itẹ nigbana lẹsẹ, awọn kan ni akọwe Ijọba Ẹgba, Ọlọla Adegboyege Ẹdun ni ko mo ẹto to daradara.

Ṣugbọn nibiti gbogbo ọtẹ igbana jasi oju gbogbo awa Ẹgba ni o to o ; eleyi si kọ wa lọgbọn.

Ọtẹ atijọ ti awọn baba wa yi ni ko tijẹ ki ilu Ẹgba lọ siwaju ju bayi lọ. Nitorina mo fi ori Lisabi bẹ ẹnyin ọmọ Ẹgba ẹ maṣe ba wọn lowọ ninu ọtẹ ti o bẹ silẹ ni Ipinlẹ Iwọ-Orun yi, adura ni ki a gba fun wọn ki gbogbo rẹ le roju.

Ago Ẹgba Ebute-Metta — Emi ni, O. Baiyewu

## Alheri Omo Hausa

Ẹ gba mi laye lati kan saara si Ọgbẹni Mallam Alheri ọmọ Hausa ti o ba awa Yoruba sọrọ ninu iwe yin ti ọsẹ ti o kọja yi, ti o ni ọkanjua owo ati ikorira okan ni o mba awa Yoruba ja.

Nitotọ ni ọro yi.

Emi paapa ti ṣe akiyesi iwa ifẹ ti awọn Hausa nmọ nlo si ara wọn nigbati mo wa larin wọn, ti mo nṣe iṣẹ-owo ni Gusau titi de Kaura Namoda.

O ko le mọ ẹniti o ni owo larin wọn; inu awo ọbẹ kanna ni nwọn jọ njẹun. Ẹniti o ba lowo lọwọ a fun ẹniti ko ni.

Ṣugbọn bẹkọ lọdọ awa Yoruba; ọmọ wa ati iyawo wa nikan ni a mọ. Awọn oṣelu wa ti a nran lọ si ile Igbimọ le ṣe igberaga pupọju.

Alheri ọmọ Hausa, o ṣe pupọ, boya nwọn le ronu piwada.

Ibara, Abẹokuta. — Emi ni, E. Laitan.

# Mallam Alheri A Dupe

Inu mi yio dun pupọ ti ẹ ba le gba mi laye ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ lati fesi si ọrọ pataki ti Mallam Alheri ọmọ Hausa kọ sinu iwe na ninu ọsẹ to kọja yi.

Ọgbẹni Alheri (tabi Mallam ni ki npee?) ni gbogbo wahala ti o nde ba awa Yoruba awa funrawa ni a nfọwọ ara wa fa wọn. Bẹni ṣugbọn awọn ẹgbọn rẹ ni Kaduna mba wa f'ọwọ kun un. Mo fẹ ki Alheri mọ wipe awa Yoruba, na ni a la nwọn loju bi a ko tilẹ ni ife ara wa.

Ẹnyin Yoruba paapa ni a ri ba wi: boya bi nwọn ti nsọ alebu ara wa fun wa yi a le ronupiwada ki a mọ lo ifẹ si ara wa nibikibi.

Emi ni,
Oniyanrin, Ibadan — M. Akiọde

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Onigbagbo Ododo

Nwọn ni bo kirun, bo si kirun niṣo ni Mọsalasi; emi Ayiluka lọ si Mọsalasi ni ọjọ Aiku (Sunday) ijeje yi. Emi pẹlu awọn ojulowo Alufa, awọn Lemọmu, awọn Alhaji ati Alaja pẹlu awọn ọmọ kewu ni a jọ lọ si ibi aṣeyẹ lati fi okuta ipilẹ ile Mọsalasi kan lelẹ ni Idita. Ibi aṣeyẹ ti Mọsalasi na kamọmọ. Ọrọ na di ọrọ Olowo nda bira. Ẹniti ko lowo ko gbọdọ ba wọn de bẹ ni.

Mo ti ri Alhaji Ekemọde tipẹ a fi ohun rẹ ti mo nia ngbọ nigba gbogbo ninu redio lojojumọ. Ki a mọ purọ, Alhaji Ekemọde wa ninu awọn onigbagbọ ododo ti mo le fi ọwọ sọ aya fun pe a wọ Alujanna. Emi ko le sọ temi o, nitoripe nko nlọ si Mọsalasi dede nko si ngbawẹ lasiko, kikirun mi paapa ko rin tara, ṣugbọn bi olotitọ ki ba ku si iro ika, a jẹ wipe emi na a de Alijanna nitoripe mo ni ifẹ arakunrin mi ati arabinrin mi l ọ k a n pupọ ju. Ifẹ si ni akoja ofin Ọlọrun Iyẹn bẹ.

## Lemomu Kekere

Mo ki gbogbo ẹnyin Musulumi Idita pe ẹ ku inawo ti Mọsalasi tuntun ti ẹ nkọ na. Anabi yio ba yin gbee dori; ṣugbọn ki ẹ maṣe gbagbe mi o ti aye ipo Lemọmu kekere ba ṣi silẹ, nitoripe emi na fẹ ipo oye Lemọmu lati jẹ, mo si mọ kewu ke diẹ afi ilu Mẹka ti nko ti lọ. Boya kewu ti mo ke ni Ilọrin pẹlu wala ti mo fọ ni Bida lọdo Alufa Tapa le ran mi lọwọ.

Bi kewu mi ko ba wa to awọn ọrẹ mi, awọn ọmọ Idita wa juburata lati ran mi lọwọ. Awọn bi Baba Pọta (Port-Harcourt) Muranọ Thompson pẹlu aburo rẹ Taju (Ọmọ Iya Fadaka), I.A.S. Adewale (Ọmọ Iya Onidita ti ẹ npe ni the Boy is Good), S. M. Onigbanjo ati bi iru awọn "Baalẹ" ọmọ Aranmọletiẹṣọ Williams pẹlu Akanbi Lasisi ("Ya Alpa").

## Agbelebu Nkrumah

Agbelebu olukuluku ọtọtọ ni: ti Jesu Krisiti lọjọ kinni lọhun, igi ni. Bi igi iroko ni, bi igi arere ni, boya igi gedu ni nwọn fi kan an, Ọlọrun nikan lo mọ, sugbọn mo gbọ wipe agbelebu na ko wuwo to AGBELEBU NKRUMAH, ỌLỌRUN ilu awọn AGANYIN. Agbelebu bọmbu (bomb) ẹlẹtu oloro ni tirẹ.

Mo gbọ wipe bọmbu ti nwọn ju si i nijọsi pa a lara diẹ, rabọ rabọ rẹ si wa lara rẹ di isisiyi, sugbọn awọn ọmọlẹhin rẹ ko fẹ sọ ọrọ na fun araiye gbọ ni. Agbẹ ti o purọ wipe on pa igba ebu iṣu ni, ara rẹ lo wa.

## Onigba Ojule

Mo ba Ọgbẹni Krobo Edusei, Minisita onigba ojule ti Nkrumah fi igba kan rọ loye, yọ nitoripe o ti tun pe e pada sẹnu iṣẹ Minisita alamojuto nkan ọgbin. Ayiluka ni nibo ni ẹ gbe fori ọrọ ibusun-ọba oni omi golu ati ile igba-ojule rọ si? Tabi Ijọba ti gbẹsẹ le wọn?

Edusei, bami ki OLUGBALA ACCRA pe o ku irọju o, Odumare a ba wa to gbogbo egungun ẹhin ti o rọ pada sipo wọn.

## Pedro Gbo'mogb'omo

Orisirisi awọn gbomogbomọ ti o wa laiye, ti Ọgbẹni Olusọla, ẹni ti gbogbo yin mọ ni Tiger Pedro Yato iṣẹ gbọmọgbọmọ tirẹ lo ju larin awọn wundia ọmọ ile-iwe ati awọn tisa wọn lọ. Ninu ọsẹ ti o kọja yi ni adajọ kotu kan ni Yaba tun ju Tiger Pedro sẹwọn ọdun kan ano fun ẹsun pe o ba tan olukọni ọmọge kan ti nwọn npe ni Comfort Nwoko lọ ṣe pẹlu agbara.

Eleyi ni o di ẹkẹdogun ti Tiger nlọ sewo nitori awọn ọmọge. Mo gbọ wipe ọmọ Ijebu ni Olusọla Tiger ṣugbọn o kọ jalẹ lati nẹ ninu ọmọ ilu ẹnẹ nitoripe nwọn ko mere ṣe bi t'Eko, we ma rẹni kani-ka-Eko Ijẹbu ni Ayiluka fọ yẹn.

Ẹ jọwọ, ye ẹni, ẹba Tiger wa iyawo ọmọge ti o ba jade lẹwọn. Ko ba ṣe ọmọge kan lati Ijẹbu-ode tabi l'Omu tabi l'Ogere. Ijẹbu ni Ijẹbu njẹ.

## Omuti Ilu Oyinbo

Emi Ayiluka ri iwe gba lati ilu Oyinbo pe awọn ọmuti' parawu ilu na ko gba iyi mọ lati ijẹta nitoripe ofin tuntun kan ti o jade fẹnu awọn ọmuti gbo ile lọ dọ adajọ ninu Kotu. Awọn oṣelu ilu Gẹsi fun awọn adajọwọn laṣẹ pe ki o fi iya ẹlẹta jẹ ẹniti o ba mu ọti amupara larin ọsẹ. Ọrọ re o, Ọlọla Tafawa Balewa.

Mo ro wipe o ye ki a gbe ofin ọmuti jade fun gbogbo awọn Ijọba Apapọ, emi ko fẹ ofin onibilala ti nwọn ṣe ni Kaduna, Zaria, Bauchi ati Kano nitoripe ko di awọn Kanuri lọwọ wipe ki nwọn mọ mu burukutu a-mu-tọ si sokoto. Mo tilẹ gbọ wipe ọti ẹmu ati burukutu ko ka awọn ara Bọrọnu (Kanuri) lara mọ nisisiyi ogogoro loku ti nwọn nfi ṣe aiye.

Bi ọrọ mi ba dabi irọ ki o lọ si Apapa Ajegunle tabi ni Ọbalende ni "deare Jimọ" wa ba MUTANI Bornu de mutani Sokoto, Katangora, Kano de Zaria kunma ku na dunia de jia; nibiti nwọn gbe nfọti wẹwọ.

## Oko Taba Igbo

Ọrọ ọti ogogoro yi lo je ki nniran oko taba igbo kan ti awọn ọtẹlẹmuyẹn ọlọpa ri ni Auchi ni agbegbe Ibini. Mo gbọ wipe oko rọba ko lowo lori to ewe-taba igbo (Indian Hemp) yi mọ. Bi o ba ti le gbe'ku ta, ti o ko ba kẹwọn, apo kan ewe-taba igbo to fi ṣe ọla ki o tun ran ọmọ lọ si ilu Oyinbo ninu owo rẹ, sugbọn ọran ọlọpa to! to!! to!!!

# E ma se f'omi sofo



# Ara Idita

( O pẹrẹ loju ewe kẹta)

Ki nwọn to bẹrẹsi fi okuta ipilẹ Mọsalasi na lẹlẹ ni Alhaji M. K. Ekemode, ti bẹrẹsi sọrọ ti o mbẹbẹ wipe o jẹ nkan ti o ni ibukun pupọ ti awọn ti o wa sibẹ ba le fi owo owọ wọn ba Ọlọrun ṣowo. Owo lati ma fi kọ Mọsalasi na ti nwọn ri gba lọjọ na si pọ jọjọ. Olukuluku ni o fi cwo dabira nibẹ.

Ẹniti nwọn kọ pe ki o fi okuta ipilẹ Mọsalasi na lelẹ ni Alaga ọjọ na, Ọgbẹni Adelagun. Lẹhin eyi ni Alhaji Tijani ti o ṣe aṣoju fun Oloye Edu ti ko le wa, ba tun lọ fi okuta ipilẹ apakeji lelẹ, gbogbo enia si patẹwọ fun gbogbo wọn. Awọn Ẹnikẹta ti nwọn tun pe ni awọn obinrin meji pataki ti nwọn duro ni iduro asiwaju fun gbogbo awọn obinrin Idita: awọn na ni Iyafin Amu Savage (Iya Onidita) ati Alaja Ṣafuratu Onigbanjo (Iya Onilẹkẹ) awọn na si fi okuta ipilẹ ti nwọn lelẹ ni ẹgbẹ kan.

Fun iranti awọn enia pataki meje kan ti nwọn ti rekọja si ajule ọrun, ti nwọn si ṣe nkan ribiribi si Mọsalasi na nigbati nwọn wa laiye, ni nwọn pe awọn ọmọ wọn ki nwọn wa fi okuta ipilẹ kan lelẹ loruko wọn. Awọn na ni Ologbe Daddy Karimu Thompson, Lawani Agbe Smith, Aranmọletiẹṣọ Williams, Alhaji Oloye Amọdu Tijani Oluwa, Alufa Kasumu Ekemọde, Lemọmu Sanni Onigbanjo ati Oloye Raji Onitọlọ.

Awọn diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn ti o wa si ibi aseyẹ ti Mọsalasi na ni Oloye Ashọgbọn, Oloye Onitọlọ, Oloye Wahabi Balogun, Olọla Lateef Dosunmu, Kansilọ Ọlatunji Id;wu, Alhaji Pedro, Alhaji Oshodi, Alhaji Mọlake, Alhaji Shittu Thompson, Alhaji M.O. Ariyọh, Taju Thompson, Muranọ A. Thompson, Yushau Lasisi ati Akanbi Lasisi.

---

# Ogbeni Adeoye Se Ikomo

EKO—Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn osu ti o kọja yi ni Ọgbẹni Adeoye (ọmọ Esiẹ) ṣe ikomọ ọmọ-ọmọ rẹ ti Ọlọrun fi ta wọn lọrẹ. Ni ile wọn, 20/22 Adeniji Adele Street (Moloney Bridge Street) ni nwọn ti ṣe ikomọ na. Nwọn si sọ ọmọ na ni Adedeji Bọlakalẹ Adeoye.

Ọgbẹni Adeoye ati baba ọmọ na, Ọgbẹni Adewuyi Yemi Adeoye na wabi-wọsi owo, nwọn fi onjẹ adidun ati orisrisi ọti te gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun.

Aṣeyẹ ọjọ na o larinrin, irohin ko to afojuba ni. Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni Ọgbẹni John Fatoki, Alhaji Y. Ayinla Disu (Awaiyewaṣere), awọn Ọgbẹni Solomon Adeoye, Thomas A Fatoki, Josiah Afọlayan, Maikẹli O. Ajiboye, Kelani Ọmọ-ọba Alhaji Amuda Woli ati Sawlihun Ọlamiju Adebisi Disu

Ire a kari o.

---


# Polowo
## Oja Re
### SINU IWE IROHIN ELETI-OFE


---


Advt. NO. 134

## NOTICE

### NIGERIAN HONOURS, DECORATIONS AND AWARDS

The National Committee on the award of Nigerian Honours would welcome suggestions from the general public on the following questions :-

(i) Do you consider that there should be only one set of National Awards, or do you consider that there should ALSO be Regional Awards either for services rendered to the Regions or in recognition of visiting foreign dignitaries ?

(ii) Do you consider that such awards should take form of :-

(a) titles, which qualify recipients to use letters after their names, or

(b) decorations, which qualify recipients to wear medals on ceremonial occasions, or

(c) both, or

(d) neither ?

(iii) Do you consider that Foreign Honours should be accepted by Nigerians, with or without the approval of the Federal Government ?

2. Please address all communications to :-

The Secretary
National Committee on Nigerian Honours,
c/o Cabinet Office,
LAGOS.

3. It will be appreciated if your suggestions are fowarded to the Secretary not later than the 30th of September, 1962


---

# Omo Alhaji Waidi Ilorin Fe Gbe Iyawo

MUSHIN—Awa Eleti Ọfẹ gbọ wipe Alhaji Labeka oniwaka, Ilọrin, olohuniyọ ti de si ilẹ yi fun ti iyawo kan ti nwọn fẹ se ni ọsẹ (Sunday) ọla ni Mushin. Iyawo tuntun na ni Khadijatu ọmọ Alhaji Abudu Waidi Anifowoshe ti nwọn fẹ ṣe ni 11, Agunbiadẹ Street.

Ni alẹ oni Satide ni oniwaka yi, Alhaji Labeka yio fi waka rẹ ṣe aisun nile baba iyawo na kin wọn to bẹresi si ṣe inawo igbeyawo na lọla. A gbọ wipe gbogbo ẹse awọn ọmọ Ilọrin ni yio pe sibẹ patapata.

Ẹyin iyawo ko ni mọ ẹni o.

# New Drug For Sleeping Sickness

## BENEFIT FOR WEST AFRICA

GENEVA— Sleeping sickness, which begins with fever and headaches, is remarkable because of the wastage and somnolence that characterize its later stages. Probably because of the dramatic nature of these symptoms, it is one of the continent's oldest recorded diseases, having been mentioned in the writings of Arab historians of the 14th century.

The ancestral home of sleeping sickness appears to have been West Africa and attempts to open up the continent probably helped to spread the disease. In spite of the difficulties it caused explorers, missionaries and traders, many of them battled their way through infested country and carried sleeping sickness into areas where it previously had been unknown.

### New Drugs

Drugs are now being successfully used to prevent and treat sleeping sickness in man and livestock and notable achievements have been recorded in controlling the disease by this means in West African territories and in the Sudan. Armed with modern drugs, it seems that disastrous epidemics are a thing of the past, providing that facilities are available for reaching people in time.

Prevention and treatment of sleeping sickness with drugs have limitations however. The appearance of drug-resistant strains and the relatively great administrative difficulties of reaching large numbers of people or cattle at frequent intervals have made it virtually impossible, particularly in dealing with nomadic tribes, to think of eradicating seelping sickness by this means alone.

### Iternational

Sleeping sickness may well disappear as social conditions improve, nomads are settled and more land is brought under cultivation. But these improvements may not come about until the disease is sufficiently subjugated to allow the mixed farming that is necessary to provide protein foods required for an energetic society. The cycle has been broken in several areas by eradicating the fly, by killing game and by bush clearing. Vaccination if successful would, of course, be a great advance. This aspect is under investigation.

### Disease

In spite of demonstrable progress, sleeping sickness still is a threat in Africa. Until the developing countries have organized their health and other services and until they have the necessary trained personnel and money, it will be the duty of international agencies to help in every way possible. The tsetse fly does not recognize political boundaries and only international help can prevent the situation from becoming dangerous.

International interest in trypanosomiasis dates back to the League of Nations. The first international conference was held in London, in 1925, and the second, in Paris, in 1928. The recommendations of these conferences indicate that even then the importance of the man, animal, fly relationship was fully appreciated.

**Read**

**And**

**Advertise**

**In Eleti-Ofe**



## BRITSH HOUSEWIFE FOR S. LEONE

Mrs Stella Humphries (right) of Bredbury, near Stockport, England, gratefully accepts a one shilling from one of the 125,000 subscceribers to the Oxford Committee for Famine Relief, who have pledged themselves to give one shilling per week to the cause.

Now this typical Britsh housewife will be leaving her three children in the safe hand of her husband, technical representative with a large engineering firm, to visit West Africa.

She will travel to Africa as guest of Sierra Leone Airways, and for most of her visit will be staying at the Methodist Missionary Society's hospital at Segbwema, a small town 205 miles from Freetown.

This modern 132-bed hospital is under the charge of Dr. John Wilkinson of Chorlton-cum-Hardy, near Manchester, England.

## KONIYEKAN OLOWO SAN OWO ISINKU ARA RE

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Iaiye ju pe kiṣe oninakuna ),,o si je oluṣokunrin. Fun odun mọkanlelaadọta ni o fi ṣe ojiṣẹ-ijọ (Sidesman) sọsi adagbo rẹ, o si fi ọdun mẹtala ṣe ọmọlẹhin Alufa ijọ Ṣọsi na.

Ninu iwe-ipingun ti baba olowo na fi silẹ, o ni ki nwọn fi ẹgbẹrun pọnun sarai ra jigi alaranbara ni iranti on si Ṣọsi ti on lọ; o ni ki nwọn tun mu ẹgbarun pọnun (£10,000) ki nwọn fi kọ Ṣọsi tuntun kan si adugbo kan ti nwọn npe ni Suffield Park ni ilu ti on ngbe na ki ara adugbo na le ma ri Ṣọsi lọ. O tun wa mu ọpọlọpọ owo rẹ o ha fun awọn ẹgbẹ alanu bi awọn ẹgbẹ alagbe-ebo papa, ẹgbẹ awọn afọju, awọn arọ, awọn adẹtẹ, ile ti nwọn ti ntọju awọn alaisan ati awọn to mọ ti ko ni iya.

Eyiti o pọju ninu owo rẹ awọn Alufa Ṣọsi ni o ha a fun, o si ra posi isinku ara rẹ pẹlu mariwo ti a fi nṣe ẹyẹ fun oku.

IBI IJOKO AWAMOTO INU AUSTIN S 200
DARA TOBE TO FI NMU ARE AWAMOTO
DINKU PUPOPUPO –
O NMU MOTO-WIWA RORUN PELU AISI EWU !



Mọto Austin to lagbara yi
uṣe alekun wiwa-mọto laisi ewu
nitoripe a ti ṣe e dara tobe, eyiti
yio jẹki iṣẹ rẹ jafara siwaju
si i, ki ere si ma wọle pupọ fun ọ.
Mọto S ati T 200 ni inu fifẹ, to si
bale fun ẹru kiko ; ijọ iwaju rẹ lagbara, o si njẹki
ero ẹnu dada; ejulerose rẹ njẹki mọto je wa
lẹhinrin laisi ewu. Bere pe ki a wa-a wo ki o ri i.

AUSTIN

S 200

(S 200 . . . .)

AUSTIN

S 200

Nigeria Head Office 237 – 241 Igbosere Road
Private Mail Bag 2063, Lagos. Garages at Aba
Apapa, Benin, Enugu, Ibadan, Jos, Kano, Lagos
Onitsha and Port Harcourt.

SCOA Motors

### ỌRỌ IWADI ẸNKUARI

## Dokita Maja Bo Awon Loja Egun

Ẹnu ya ọpọlọpọ awọn enia ti nwọn pejọ si gbongan-igbẹjọ nibiti nwọn nṣe iwadi lori ọrọ ajọda iṣẹ mẹfa Ijọba ti Ipinlẹ Iwọ orun, nigbati Dokita Akinọla Maja, Babasalẹ Ẹgbẹ Afẹnifẹre bẹrẹsi bọ awọn kuro loju egungun, ti o ntu pinpin nkan ti awọn ṣe ki ina to jo'le. Ijọ mẹrin gbako ni Dokita Maja ṣe ninu apoti ẹleri niwaju awọn oluwadi na.

Dokita Maja ni awọn mẹrin ni awọn da ẹgbẹ akọle ti nwọn npe ni National Iuvestments and Properties Company Ltd silẹ. O ni ọkẹ o le ẹgbẹdọgbọn pọnun (£25,000) ni ipin (shares) ti on ninu owo idasilẹ ẹgbẹ na, sugbọn on ko ti san kọbọ kan ninu owo yi nitoripe Oloye S. O. Shonibarẹ sọ fun on wipe awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifere (AG) lo ni ẹgbẹ onisowo na, Afunnisọ ni on (Dokita Maja) jẹ nibẹ.

Dokita Maja ni on niran igba kan ti awọn ẹgbẹ onisowo yi san owo kan gọbọyi (£2,100,000) si apo ẹgbẹ Afenifẹre (AG) ni Ibadan. Nigbati awọn san owo na fun Oloye S. O. Lanlehin, akapo ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) on ṣebi fun ilọsiwaju iṣẹ ẹgbẹ NIPC ni awọn san an fun, ti on ba mọ wipe ọna miran ni nwọn fẹ gbe owo na gba ni on ko ba ti lọwọ nibẹ.

Dokita Maja ni on ati Oloye Adebayo Doherty ni awọn ra ilẹ kan ti nwọn npe ni Mọba lọwọ awọn ọmọ Oloye Onikoyi ni iwọn ọkan bi odun kerin sehin ni ẹdẹgbafa pọnun (£11,000) sugbọn larin oṣu kan na ni awọn ta ile na fun Ọgbẹni kan ti o njẹ Allison ni egba wa pọnun (£20,000)

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370 EDITOR (OLOTU): OLA ONATADE
15, Kosoko St., Lagos.